# ÀLÌKÁMÀ ATI ÈPÒ

## Matteu 13:24-30, 36-43

## ẸKỌ 76 FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Bikoṣepe a tún enia bí, on kò le ri ijọba Ọlọrun" (Johannu 3:3).**

**A Ṣeleri Ọba**

Ninu awọn owe ti a n kọ́ ẹkọ nipa rẹ yii, Jesu n fẹ ki awọn ọmọ-ẹyin Rẹ mọ ohun ti Ijọba Ọrun tumọ si. Wọn mọ diẹ ninu ẹkọ ti awọn wolii, wọn si mọ pe a ti ṣeleri Ọba kan fun wọn, Ẹni ti yoo wa gbẹsan wọn lara awọn ọta wọn; ti yoo si jọba titi lae. Jeremiah ti kọwe pe: "Sa wò o, ọjọ mbọ, li OLUWA wi, ti Emi o gbe Ẹka ododo soke fun Dafidi, yio si jẹ Ọba, yio si ṣe rere, yio si ṣe idajọ ati ododo ni ilẹ na" (Jeremiah 23:5).

Nigba ti Jesu de, awọn ti wọn ni imọ ẹmi mọ Ọn bi Ọba naa. Iwe Mimọ́ sọ nipa ti Josẹfu ara Arimatea, ẹni ti o beere oku Jesu, pe oun paapaa "pẹlu nreti ijọba Ọlọrun" (Marku 15:43). Nigba ti Natanaẹli dahun ipe Jesu, o wi pe: "Rabbi, iwọ li Ọmọ Ọlọrun; iwọ li Ọba Israẹli" (Johannu 1:49). Jesu sọ fun awọn eniyan naa pe asọtẹlẹ Sekariah n tọka si Oun pe: "Yọ̀ gidigidi, iwọ ọmọbirin Sioni; ho, Iwọ ọmọbirin Jerusalẹmu: kiye si i, Ọba rẹ mbọ̀wá sọdọ rẹ: ododo li on, o si ni igbalà; o ni irẹlẹ, o si ngùn kẹtẹkẹtẹ" (Sekariah 9:9; Matteu 21:5). Ọrọ ti a kọ sori agbelebu ti a kan Jesu mọ́ ni wọnyii: "EYI NI ỌBA AWỌN JU."

Bayi ni a ri i pe Jesu jẹ́ Ọba, awọn ọmọ-ẹyin Rẹ si gba eyi gbọ́. Ṣugbọn ọba gbọdọ ni ijọba; awọn ọmọ-ẹyin Kristi si n fẹ mọ igba ti Oun yoo gbe ijọba Rẹ kalẹ. Wọn n reti pe Oun yoo bi ijọba Romu, ti o ti fi awọn Ọmọ Israẹli sinu isinru fun ọdun pupọ ṣubu lọna iyanu, ki o si jẹ ki wọn gbadun ijọba ominira ni ilẹ Palẹstini. Wọn le maa fi ọkàn wọn wo Jesu lori itẹ ti ayé yii ati awọn pẹlu ni wiwa ni ipo pataki ninu aafin Rẹ. Lẹyin ti Jesu tilẹ ti sọ fun wọn pe Oun n lọ si Jerusalẹmu lati kú, wọn n jiyan nipa ẹni ti yoo tobi ju lọ ninu Ijọba Rẹ. O dabi ẹni pe wọn ko mọ pe Ijọba Ọlọrun ki i ṣe "jijẹ ati mimu; bikoṣe ododo, ati alafia, ati ayọ̀ ninu Ẹmí Mimọ́" (Romu 14:17).

**Ijatilẹ Awọn Ọmọ-Ẹyin**

Nigba ti Jesu wọ Jerusalẹmu pẹlu ayọ iṣẹgun nla laaarin ogunlọgọ eniyan ti wọn hó iho iyin, ọkàn awọn ọmọ-ẹyin balẹ pe akoko naa de tán nigba ti yoo fi ara Rẹ̀ ṣe Ọba awọn Ju. Nisisiyii wọn yoo ri i pe a tẹ ori awọn ara Romu ba, awọn naa yoo si bi awọn alakoso ilu wọn ṣubu. Bawo ni ijatilẹ wọn ti pọ to nigba ti wọn de Jerusalẹmu ti Jesu kò si fi ami ijà hàn! Dipo eyi, laaarin ọsẹ kan, O kú ikú ori agbelebu.

Lọna Emmausi, lẹyin ti a ti kan Jesu mọ́ agbelebu, a ri meji ninu awọn ọmọ-ẹyin yii ti wọn n sọ nipa ijatilẹ wọn pẹlu ibanujẹ. Wọn wi pe "Bẽni on li awa ti ni ireti pe, on ni iba da Israẹli ni ìde" (Luku 24:21); ṣugbọn nisisiyii O ti lọ a ko si ti i gbe ijọba kankan kalẹ!

**Ijọba Kristi**

Ṣugbọn ki ni a mọ nipa Ijọba Kristi? O ti wi funra Rẹ pe Oun ni Ọba; ọba si ni lati ni ijọba. Nigba naa, awọn wo ni wọn wà ninu Ijọba ti o ni lati tẹriba fun Jesu?

Johannu Baptisti ti kede pe "Ẹ ronupiwada; nitori ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ̀" (Matteu 3:2). Njẹ o ṣe iṣe bi? Njẹ Jesu fi ayé yii silẹ bi ẹni ti a ṣẹgun Rẹ̀? Bẹẹ kọ rárá! Ijọba naa ti bẹrẹ; a ti fi ipilẹ Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun lelẹ, nigba ti Jesu yoo jẹ Ọba, ati pe "yio fi ododo ṣe idajọ talakà, yio si fi otitọ ṣe idajọ fun awọn ọlọkàn tutù aiye, on o si fi ọgọ ẹnu rẹ lu aiye, on o si fi ẽmi ète rẹ lu awọn enia buburu pa" (Isaiah 11:4). Jesu ti wá si ayé, O si n ko awọn ọmọ ibilẹ Ijọba Ọrun naa jọ sọdọ ara Rẹ; nigba ti O si pada lọ si Ọrun, O fi aṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ lati lọ si gbogbo ayé ki wọn si pe gbogbo eniyan si ironupiwada, ki wọn ba le ni ipo ninu Ijọba Ọrun naa. "Bikoṣepe a tún enia bí, on kò le ri ijọba Ọlọrun" (Johannu 3:3). Nitori naa, lẹyin ti awọn ọmọ-ẹyin gba ifiwọni Ẹmi Mimọ́ ni Ọjọ Pẹntekọsti, wọn jade lọ lati waasu igbala ti yoo mura awọn ọmọ ibilẹ Ijọba Ọrun naa silẹ. Awọn alufaa Ọlọrun tootọ n waasu ọrọ kan naa lonii, "A kò le ṣe alaitún nyin bi." Ẹmi Ọlọrun si n pe ọkàn awọn eniyan fun Ọba Ogo ti yoo tun pada wa sinu ayé yii lati jọba pẹlu awọn eniyan mimọ Rẹ fun ẹgbẹrun ọdun.

**N Dagba Pọ̀**

Nigba ti Jesu pa owe alikama ati epo fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ o wi pe baale ile naa sọ fun awọn iranṣẹ rẹ pe ki wọn jẹ ki epo ati alikama maa dagba pọ titi di akoko ikore. Nigba naa ni oun yoo paṣẹ fun awọn olukore lati kó epo jọ si apa kan, ki wọn si sọ wọn sinu iná. Lẹyin naa ni a o kó alikama sinu abà fun lilo.

Jesu wi pe irugbin rere jẹ apẹẹrẹ awọn ọmọ Ijọba, nigba ti epo si jẹ apẹẹrẹ awọn ọmọ Eṣu. Oun ki yoo mu awọn eniyan Rẹ kuro ninu ayé lẹsẹkẹsẹ ti wọn ba ri igbala, ṣugbọn wọn ni lati maa gbe ninu aye pẹlu awọn ẹlẹṣẹ titi di akoko ikore, nigba ti Oun yoo rán angẹli kan wá lati ya awọn eniyan rere sọtọ kuro laaarin awọn eniyan buburu. A o ji awọn ti o ti ku dide a o si yà wọn sọtọ̀ lọna kan naa gẹgẹ bi awọn ti wọn wa laaye nigba opin aye. "Oluwa mọ̀ bi ã ti íyọ awọn ẹni ìwa-bi-Ọlọrun kuro ninu idanwo, ati bi ã ti ípa awọn alaiṣõtọ ti a njẹ niya mọ dè ọjọ idajọ" (2 Peteru 2:9).

**Eso Ẹmi**

Boya ninu awọn “èpo” le fi ara jọ awọn Onigbagbọ. Nigba ti awọn irugbin wọnyii wà ni kekere, a ko le mọ iyatọ; ṣugbọn nigba ti awọn eso farahàn, awọn iranṣẹ mọ pe èpo wà laaarin alikama naa. A mọ̀ pe awọn Farisi jẹ alafarasin pupọ, wọn si gba pe ọmọ Abrahamu ni awọn i ṣe, ṣugbọn nitori ẹ̀ṣẹ wa ninu ọkan wọn, Jesu wi fun wọn pe “Ti eṣu baba nyin li ẹnyin iṣe” (Johannu 8:44). Ni akoko miiran Jesu wi pe, “Eso wọn li ẹnyin o fi mọ̀ wọn” (Matteu 7:16). Itumọ eyi ni pe iwọ yoo mọ awọn ti i ṣe ọmọ Ijọba Ọrun ati awọn ti wọn jẹ ọmọ ọta nì nipa iwa wọn. Awọn ọmọ ibilẹ Ijọba Ọrun ni iwa wọnyii “eso ti Ẹmí ni ifẹ, ayọ̀, alafia, ipamọra, ìwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ́, ìwa tutù ati ikora-ẹni-nijanu” (Galatia 5:22, 23).

**Itara Odi**

Inu awọn iranṣẹ baale ile yii kò dùn lati ri èpo ti o n dagba laaarin alikama, wọn si fẹ fa wọn tu kuro lẹsẹkẹsẹ. Èpo jẹ eweko ti o n lọ ara rẹ mọ irugbin rere, o si ṣoro lati fa a tu kuro lai fa alikama tu pẹlu rẹ̀.

A kà ninu itan ijọ Onigbagbọ nipa akoko kan nigba ti o jẹ pe awọn alaṣerege ẹsin yoo ni itara odi fun ohun ti wọn gbagbọ to bẹẹ ti wọn a maa pa ẹnikẹni ti ko ba fi ara mọ wọn. Ni igba aye Kristi, nigba ti awọn ara Samaria kò gba Jesu gbọ, awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ fẹ pe iná sọkalẹ lati Ọrun wá lati pa wọn run, ṣugbọn Jesu ba Jakọbu ati Johannu wi, O si wi fun wọn pe Oun ko wa lati pa ẹmi eniyan run bi ko ṣe lati gbà wọ́n là (Luku 9:52-56).

Alikama ati epo ti n dagba pọ nigba naa, wọn ṣi n dagba pọ sibẹ titi di isisiyii. Nigba ti opin aye ba de akoko ti a o sun epo ninu ọwọ́ iná, Jesu yoo “san ẹsan fun awọn ti kò mọ Ọlọrun, ti nwọn kò si gbà ihinrere Jesu Oluwa wa gbọ́: awọn ẹniti yio jiya iparun ainipẹkun lati iwaju Oluwa wá” (2 Tẹssalonika 1:8, 9).

**AWỌN IBEERE**

1. Apẹẹrẹ ki ni eso rere jẹ́?
2. Awọn wo ni èpo?
3. Titi di igba wo ni alikama ati èpo yoo maa dagba pọ̀?
4. Bawo ni a ṣe le di ọmọ ibilẹ Ijọba Ọrun?
5. Ta ni Ọba naa?